*Ireti Eda…!*

**EPISODE 14**

**<u>Characters</u>**

*Abokede*
*Bello*
*Wosilat*
*Alaba*
*Mrs Animashaun*

---

**Scene 1**
**Ilorin. Animashaun's residence. Early moring!**

1. **SFX**: **<u>CAR STARTS! CAR HORN BLOWN TWICE, SOUND BED OF MORNING IN A LUSH GARDEN, BIRD CALL OR CRIES ETC.</u>**
2. **BELLO**: (**IMPATIENTLY, ON MIC**) Oooohhh! Nibo ni Baba yii tun gba lo, taa lo ma si gate bayii? (**HORN BLOWN AGAIN**)
3. **SFX**: **<u>CAR DOOR OPENS AND CLOSES SHARPLY</u>**
4. **BELLO**: (**MUTTERING TO HIMSELF**) Kin ni nkan taa mo to mu Baba yiifise re sile bayii laaro kutukutu.
5. **SFX:** **<u>LOUD KNOCK ON THE GATE</u>**
6. **BELLO**: (**SHARPLY, LOUD**) Tani? **(FRUSTRATED, LOWER VOICE)**Gateman da?
7. **ABOKEDE**: (**NERVOUSLY OFF MIC**) Emi ni o Abokede loruko mi, e jowo Mr Bello ni mon beere o.
8. **SFX**: **<u>GATE OPENS</u>**
9. **BELLO**: Kin lo fe kin se fun e?
10. **ABOKEDE**: (**RELIEVED**) Olohun seun. Ekaaro sir, oruko mi ni Abokede.
11. **BELLO**: (**INTERRUPTS IMPATIENTLY**) Mo ti gbo, emi ni Bello Animasahun, kin ni ofe kin se fun o?
12. **ABOKEDE**: Ko si sir, mo kan wada bagi te gbage sodo wa pada fun yin ni
13. **BELLO**: Bagi wo?hone yin
14. **ABOKEDE**: Eleyii ni sir!
15. **BELLO**: (**SHOCKED**) Iro ni o? (**STUTTERS**) Bawo loti se?
16. **ABOKEDE**: E wa sodo mi lati ra card ti e ma fi load phone yin le gbagbe e si shop wa. ki nto mo e ti wako lo .
17. **BELLO**: Joo duro na
18. **SFX:** **<u>RUMMAGING THROUGH THE BAG</u>**

19. **BELLO:** Joo ki lo pe oruko re na?

20. **ABOKEDE**: Abokede ni sir!

21. **BELLO**: Abokede! Se osi bagi yii wo?

22. **ABOKEDE**: **(NERVOUSLY)** Beeni mo si wo, kin le mo address ile yin ni ki nsi le gbe wa fun yin. Ema binu, atana ni mi o ba ti gbe wa sugbon ko seni to le bami duro ni shop, asi pe ka to close lana. Nnkan to fi je pe aaro ni mo gbe wa niyen.

23. **BELLO**: Se o ri nkan to wa ninu bag yii sa?

24. **ABOKEDE**: Beeni ni mori pe awon owo ile okeere ati awon iwe lonirannran lo wa nibe, sugbon n fowo kan nkankan nibe o afi address nikan ti mo ko jade….

25. **BELLO**: Fokan re bale. Mo mo pe o fowo kan nkankan nibe naa ni nkan to n yami lenu……. .joo ma binu si bimo ti se sio nigba tio koko wole. O ya wole sinu motor ki ngbe o die. Mo n jade lo de yen

26. **ABOKEDE**: E ma se yonu, mo gbodo tete pada sibi ise ni kiakia bayii, moti pe.

27. **BELLO**: Sugbon sibe naa o ye ki nfi emi imoore han si o.

28. **ABOKEDE**: **(SURPRISED)** Emi imoore han abi ki le so?

29. **BELLO**: Wo Abokede, mo mo pe ko sona ti mofi le san esan oore yi fun o.

30. **ABOKEDE**: Mr Bello, n o reti ebun Kankan lati odo yin fun nkan ti mose yii. Nkan ti mo mo nipe e o ti maa wa bag yin, bee sini e le ma mo pe shop wa le gbagbe e si.

31. **BELLO**: Okay. (**OPENS THE BAG**) Gba $100 yii, abi naira lo fe? Je kin wole ki n lo mu wa.

32. **ABOKEDE**: (**NERVOUSLY**) E wo Mr Bello n ofe nkankan, n o se n timo se tori Owo

33. **BELLO**: Joo….

34. **ABOKEDE**: **(HURRIEDLY)** Rara! E wo mo ti lo

35. **SFX:** **FEET HURRYING AWAY**

36. **BELLO**: (**CALLS OUT**) Abokede! Abokede, duro(**TO HIMSELF…** Wow, n o ti gba nnkan to sele yii gbo o, abi mo n sun ni..Edakun eji mi ti mo ban sun o

37. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 2**

**Ilorin! Alaba's shop. Morning**

38. **SFX:** <u>**AMBIENCE OF A MARKET PLACE. NOISY OFF MIC**</u>

39. **WOSILAT**: E kaaro n biyi o (Good morning o)
40. **ALABA**: (**HAPPILY**) Ah Wossy ken ke. Boo ni gbogbo nkan?
41. **WOSILAT**: Alawurabi laa n dupe fun Daddy Alaba
42. **ALABA**: (**FEIGNED ANNOYANCE**) Wosilat, se o tun ti de pelu isolenu, ewo ni Daddy Alaba. Daddy Alaba se emi ni Baba Alaba ni ? pe mi looko mi, Alaba ni mi
43. **WOSILAT**: (**LAUGHS**) Ah, emi o le pe yin looko o, e ju mi lo.
44. **ALABA**: Enh enh? Nigba na nko?
45. **WOSILAT**: (**LAUGHS**) O daa o, Boda Alaba abi iyen nko? Gbogbo bo ti wu kori Owo ni mo mu wa. E seun mo dupe , e ku agbaale mi ni gbogbo igba.
46. **ALABA**: (**HAPPILY**) Ah Wossy ken ke. Ojulowo onibara mi ni o. Gbogbo igba lo ma nse deede nipa kiko Owo mi wa la siko. O yato sawon mii taa sese maa le kiri ki won to sanwo.
47. **WOSILAT**: Boda Alaba, Olohun ma se wa ni afibi solore. Eyin tie gbami lawin, n se wa ko owo yin dani lai ni wa san-an lasiko.
48. **ALABA**: Wosilat, iwo je eni to mo on ni. Awon kan wa won o ma je mii mon torun won ni..
49. **WOSILAT**: Ah! Won jo ye abara mo ore je niyen o (they are ingrates then)
50. **ALABA**: Iwo tie yato si won gidi gan ni. Iwo naa mo ara re, Omo to shon(beautiful woman)
51. **WOSILAT**: (**LAUGHS**) Ah, mo si mo Iyawo yin nile egbin niwon.
52. **ALABA**: ………………… Iwo na wo iduro re…
53. **WOSILAT**: (**CHUCKLING**) E jo e sora yin ti Oko mi ba gbo nkan ti e n so ko ma ni mo pe ere le nse.
54. **ALABA** **Se o ma n jowu ni? Sugbon o ye ko mo pe eni ba ti ni fe arewa bii i ru re yii Oju gbogbo ni yo ma wo o.**
55. **WOSILAT**: Eyin le mo . (**CHANGING THE SUBJECT**) E dakun e wa fun mi loja ki n ma lo. Se oja titun eyi ni ?
56. **ALABA**: Tomato alagolo ni?
57. **WOSILAT**: Mo mo.
58. **ALABA**: Won sese n se iru re ni, o si daa gan-an ni
59. **WOSILAT**: Se looto? Se e ofi kun oja funmi?
60. **ALABA**: Awon ti n ra oja palipali ni mo n ta fun
61. **WOSILAT**: Ha, o daa bahun, awa o le raa nuhun.
62. **ALABA**: (**FLIRTINGLY**) Sugbon iwo naa le mu, mo kuku mo pe o tete san Owo pada fun mi kiakia.

63. **WOSILAT**: E seun o. Eyin naa kuku mo pe bi mo ba ti n taa ni maa mu Owo yin wa fun yin.

64. **ALABA**: Ko si yonu. Ki lo tun fe Wossy mi kenke. (**CALLS OUT**) Iwo wa, ki owa baa gbe eru yii.

65. **WOSILAT**: E seun mo dupe o.

66. **ALABA**: Gbogbo igba ni e se e se, asi se nnkankan.

67. **WOSILAT**: (**LAUGHING**) Boo ni n ba ti wa dupe o? O daa o ipade tun di ose to mbo o. E seun mi o.

68. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 3**

**Ilorin! Animashaun's residence. Evening!**

69. **SFX**: <u>**DOOR OPENS AND CLOSES ABRUPTLY**</u>

70. **MRS ANIMASHAUN:** (**ON MIC)** Bello! kaabo.

71. **BELLO**: (**SURPRISED. COMING ON**) Mummy. Ibeyen le wa.

72. **SFX**: <u>**KISSES**</u>

73. **MRS A**: Bo nise lonii? Baba yin nko?

74. **BELLO**: Mo fi'won sile ni Office ni tori mo tete kuro. Mo ma wo baalu lale yii lo sibi ti mo nlo.

75. **MRS A**: Nibo lo n travel lo?

76. **BELLO**: UK ni

77. **MRS A**: (**SURPRISED**) Bawo lo ti fe rinrin ajo lai niwe irin, abi sebi o sope gbogbo iwe irinna re ati Owo lo sonu pe u bag e lana.

78. **BELLO**: (**CHUCKLES**) Mummy, e le gbagbo mo ma ti ri bag mi.

79. **MRS A**: **(EXCITED)** iro ni o, bawo lo tii rii?

80. **BELLO**: (**HAPPILY**) Mummy, Omobinrin kan lo ma sile wa laaro yii, lo ba gbe bag mi wa. O so pe shop awon ni mo gbagbe e si. O ni address loun fi mo ile wa.

81. **MRS A**: (**BEWILDERED**) Bello, nnkan to n so ko ye mi o. Omobinrin wo? Ni shop wo? Bawo lo se mo address se ko ri gbogbo nnkan naa ninu bag ni?

82. **BELLO**: (**LAUGHS**) Mummy, o ya mi gan lenu, afi bi eni pe mo n lala. O ni oun ri Owo, passport, visa ati gbogbo nnkan yo ku to wa nibe.

83. **MRS A**: O ri, o situn daa pada? Dollar lona egberun ti kii se die, ta ni Omo naa?

84. **BELLO**: Abokede ni, o n ta recharge card ni kiosk kekere kan legbe ona nibe yen. Mo mo pe mo si le mo shop e daadaa.

85. **MRS A**: Ara o n o ri iru eleyi ri o, ki lo wa fun un nigba to nlo?

86. **BELLO**: Gbogbo nnkan ti mo fe fun ni ko ma gba. N se lo tese morin to lo.

87. **MRS A**: O da bag re pada, o si tun ko lati gba nnkankan lowo re. Se ooto si ni nnkan to n so yii. Angeli ni eleyii, kii se eeyan.

88. **BELLO**: (**LAUGHS**) Kii se Angeli, o kan je olooto Omo ni. O si tun rewa pelu.

89. **MRS A**: Mo fe ri Omo naa

90. **BELLO**: Ma gbinyanju ati wa ri ti mo ba de. Inu mi saa dun pe mo tun le make meeting mi ni UK. Mo fe pe fun reschedule flight mi.

91. **MRS A** Olohun seun, sugbon o gbodo ripe o ra nnkan to dab o fun Angeli re. Mo si mo pe inu re adun bob a se bee…

92. **BELLO**: Ma raa bo fun, k'Olorun sa je ko gbaa ti mo ba raa fun ni

93. **MUSIC: BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 4**

**Ilorin. Wosilat's Kitchen! Evening!**

94. **SFX**: <u>**SOUND OF KITCHEN UTENSILS BEING USED**</u>

95. **SFX: <u>DOOR OPENS AND CLOSES</u>**

96. **ABOKEDE**: (**SURPRISED COMING ON**) Ah, Aunty Wosilat e ti dana ounje ale tan?

97. **WOSILAT**: **(ON)** Abokede kaabo.

98. **ABOKEDE**: **(ON)** Aunty Wosilat e ma binu pe o pe mi die. E jowo e je kii nse eyi to ku.

99. **WOSILAT**: Rara ma se yonu Abokede. Mo mo pe yoo ti re e lati aaro. Olohun je k'aje wa daadaa loni. Mo wa n se ounje ti Ajani feran ju fun un.

100. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES**) O da, ti e ba se obe tan, e je kin wa ro Amala

101. **WOSILAT**: O daa mo gbo. (**PAUSE**) See oni sa daa?

102. **ABOKEDE**: A dupe lowo Olohun. Mo ti da bag ti mo ri padafun eni to ni laaro yii.

103. **WOSILAT**: Enh enh? Mo mo pe inu re maa dun gan an ni

104. **ABOKEDE**: Inu re dun o. Koda o fe fun mi lowo, sugbon emi o gba o kia ni mo ya ba ese mi soro.

105. **WOSILAT**: (**LAUGHS**) Olohun baa se lo fi je iru re lo ri bag re ni, bi o ba je bee………paapaa lasiko ta wa yii t'oju Aja seje.

106. **ABOKEDE**: Olohun nikan lo mo nnkan ti o n ro, to fi gbagbe aduru Owo bahun.

107. **WOSILAT**: (**SIGHS**) Ki la-n so yii Abokede, kaluku lo ma ni nnkan to yoo labe aso. Atolowo ati talika (**PAUSE**, **SIGHS AGAIN**)

108. **ABOKEDE**: (**CONCERNED**) Aunty Wosilat, kin ni nnkan naa? Kin ni e n ro?

109. **WOSILAT**: (**HISSES WORRIEDLY**) Abokede, Alaba ma ni o.

110. **ABOKEDE**: Uncle Alaba, Oko Oga mi?

111. **WOSILAT**: Bee ni, iwo naa sa mo pe Alaba lo gba mi lawin ti mo fi n ri oja ta.

112. **ABOKEDE**: Mo mo pe eeyan daadaa ni.

113. **WOSILAT**: N o mo nnkann to ro luu, lati bii ojo melo kan bayii . O n bami sawada ako, ogboogbon ni mo fi ro ra n ye nnkan to ju simi .

114. **ABOKEDE**: Sugbon se bi won ni Iyawo nile, Aunty, boya won kan n bayin sere lasan ni.

115. **WOSILAT:** Nigba ti n kii somode, mo mo pe ko sere. Mo mo daadaa bi Okunrin ba n wa nnkan.

116. **ABOKEDE:** Ah, iwa ti o da ni. Ki wa le maa se bayii Aunty?

117. **WOSILAT**: Abokede, n o ti mo. Bi o ba se bo ti je ni abusidii ni n o ba fi se. Sugbon Alaba seeyan. Oun lo ran mi lowo lori oja mi. O ba iwo naa wa'se, o sit un so pe oun ma ba Ajani naa wa'se. N o le gb'oju agan sii. Oluranlowo ebi mi ni.

118. **ABOKEDE**: Ah aunty, boya e siwon gbo ni (**SNAPS HER FINGERS AND EXCLAIMS**) Awon Okunrin saa, k'olohun gbawa

119. **MUSIC:** **THEME MUSIC…DRAMA BRIDGE UP AND UNDER…..**